To the Chief Secretary to the Govt


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. V No 256. SATURDAY JANUARY 7, 1928. 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATOSI

:o:

[ *Fun Atosi lailai ati titun* ]

Ti a ko ba tete wo Atosi san daradara, o ma ndi enia lowo lati **se** abiamo, o si ma nfa orisi arun mi wa, bi:—Jedi-jedi, Aran, Iju, **Eda**, Ipake, Ase, Iakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atosi san lawotan patapata, ko si nje ki o fi aye wu arun mi sile.

WA O MA JO, AWA O MA YỌ NI"

ga ati Asia (*Flags*) ti Germany
işirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo
treet, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara
un akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ,
Ijẹ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere
nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

e :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

# Ero ya wa ra

DEBOYE ŞOLANKE Onişowo
abiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-
Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun
lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti,
apot
irişi atı Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ,
oris
Ọ... ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi,
ti awọn Aganyin f nko Ẹja-şawa
ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ
. 4 Idunmagbo Street, (l'ebute
) ati ni No. 19, Moloney Bridge
(l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati
iṣẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ

**Are you a Mechanic?**—If so you must want Tools, now or soon.

**Do you intend to put up a house?**—Then you will require Builder's Hardware.

In either case you cannot do better than call at

## B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

## J. C. VAUGHAN

Ti ile-ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọko ti o ri ra nibẹ ha yio şe o.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọ ... ni gbọ... ọja meremere ibẹ.

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWỌ GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor.*

## *GBOHUN-GBOHUN.*

ỌBA LO T'EHIN ERIN FỌN.

A gbọ pe Ijọba npete ati sọ fun awọn lotu Ijọ Wesley ti Ṣọṣi Ọbun Eko pe gẹgẹbi Ṣọṣi yi ti ta gan-ngan si ita ti o si i lilọ-bibọ awọn mọto lọwọ, ki nwọn wa ọrọkọ fi ṣ'ada lati ta ki aye le wa fun lilọ-bọ awọn mọto gbogbo.

ỌRAN GBOGBO KI ISE LORI ABAUM.

Bẹ na ni a si tun gbọ pe awọn Olotu Ijọ Vesley Ọbun Eko yi ntọ pinpin pupọ ninu wọn mẹmba wọn ti nwọn ni nwọn binrin pupọ ti nwọn ko si gbeyawo, gẹgbi ilana Ṣọṣi na, lati bi wọn lere pe Ewo ni ṣiṣe": irufẹ titọ-pinpin yi lo mu Ijọ Ṣọṣi Ẹlẹja bẹrẹ lọdun pupọ sẹhin. bere ti a fẹ bere lọwọ awọn Alaṣẹ Ṣọṣi yi "A ha ngbeyawo l'ọrun bi tabi a nfi n ni ni Igbeyawo?"

---

KURUKURU BETE, AMỌDUN, BAYI L'Ẹ O BA WA AMỌDUN!!!

---

"ỌBA NKI Ọ! ALAIYE NKI Ọ!!"

---

LATI ỌWỌ KEKERE- -AWO.

---

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

Mo bẹrẹ foji o,

Niwọn igbakugba ti a ba mbẹ laye ani ni alafia pẹlu irọra ani ti ọdun si nyipo loju ẹmi olukuluku wa eyi ni Amọdun, o dara gidigidi fun wa lati ma ṣe Akanṣe iwe kan ni pataki nibiti oju ilu gbe la de yi nipa awọn ohun pataki-pataki ti o ba ṣẹlẹ ni ilu wa ati nibomiran ni ẹhin ẹkun fun rere ilu ala itẹlọrun tabi aini itẹlọrun li a o ri larin wahala ti a ba ṣe si ori irufẹ ṣiṣe bẹ.

Ohun ti a nwi yi jẹ ohun anfani ti kosi tẹlẹtẹlẹ to larin wa ri bikoṣe ni ọdun ti 1926 ti a ro ori wa ti a si ri pe o tọ o yẹ ki a ma da ẹnyin ilu nide nipa ṣiṣe yi ani lori eyiti a ṣe iwe kan ti a fi bẹrẹ ni eṣi ti a si sọ ni "Ọbẹ ki imi nikun agba" ti ọpọlọpọ iwe na ṣi mbẹ lọwọ wa tidi di isisiyi fun ẹniti ko bai ti ni tirẹ lọwọ.

O dabi ẹnipe awọn ara ilẹ yi nwọn ko mọ riri iru iwe baun, bẹ iwe ti a le so wipe on lo jẹ anfani odidi iwe ti o rohin odun kan fun wa, iwe yi wa fun wa wipe bi a ba nṣe ariyanjiyan lori ohun kan ti o ba ṣẹlẹ, kisi wahala fun wa mọ lati ma sure wa iwe irohin kiri, ti olukuluku wa ba ti ni tirẹ lọwọ, ki a kan lọ n'ọwọ mu tọ lo ku; ki a si wa ohun ti a nfẹ ninu rẹ, ẹ ko ri wipe irufẹ ṣiṣe bayi o gba anfani tamutamu kuro lọwọ awọn iwe-irohin ti a ti ni jọ s'ile.

Ati pẹlu nkan omiran yio wa, ti o jẹ wipe o le sa awọn oniwe-irohin nija tabi eyiti nwọn le fi oju fo da lati fi sinu irohin nigbati ohun na ba ṣẹlẹ ṣugbọn ti ẹ le ri ka ninu iwe ti a ba ṣe ni Akanṣe laseko ti ọdun kan ba buṣe bayi.

Nigbati a o kọkọ pilẹ ohun ti a dawọle yi, ni iwe rẹ nipataki ti a ṣe gede lọdun to kọja (1926) anu diẹ lo ṣe wa lati ri pe iwe na ko tete jade bi a ti fẹ fun ẹnyin ilu, ṣugbọn iṣẹ ti Ọlọrun li eyi, nitori bi ẹda ba nro tirẹ, Ọlọrun papa yio ma ro ti Rẹ, ki Ọlọrun jẹki aniyan wa ma papọ mọ ti Rẹ o, nipa eyi lo fi dabi ẹnipe ẹlomiran ko mọ gunmọ ohun ti iwe na wa fun loju wa tobẹ ti o fi dabi ẹnipe nwọn kau wulẹ ọburo nipa iwe na ni, ti kosi bikita lati ni tirẹ lọwọ, bẹ iru iwe bẹ li a ma nwa kiri lẹhin ọla nigbati o ba yẹ lati jẹ anfani rẹ gẹgẹbi a ti wi ni iṣaju.

Mo ro wipe olukuluku wa ni yio ri "Eko Akete" ti oni lọwọ fun Akanṣe ti a ṣe yi, ati iwe "Ọbẹ ki imi nikun agba ti a sọ wipe on ni a kọkọ fi fara iru wahala ti a nṣe yi eyiti o ṣi mbẹ ni tita ni kọbọ mẹrin—mẹrin (4d.) ni ile-iṣẹ iwe-irohin yi.

A juba agba ati ọmọde, a juba ọkunrin ati obinrin, a juba olowo ati mẹkunnu, a juba onile ati alejo lakotan a juba awọn Alakoso wa pẹlu ki Ọlọrun da ẹmi Ọba King si, ki ibẹrẹ, agbedemeji ati ipẹkun ọdun (1928) yi si ṣe olukuluku wa ni ire, animọ-owo, animọ-ọmọ animọ-ilera pẹlu ẹmi gigun. Aṣẹ—Amin.

## AWỌN OHUN PATAKI-PATAKI TO ṢẸLẸ L'EKO ATI ẸHIN ẸKUN LỌDUN TI A GBE SIN YI.

1. Ọlọla Gomina Graeme Thomson K.C.B., pẹlu iyawo rẹ ṣe Awowo (*At Home*) lọjọ 4 oṣu January 1927 eyiti a pe ọpọlọpọ awọn Saraki ilu sibẹ.

2. Iku Tijani Noibi ẹgbọn Lemọmu Ligali lọjọ 4 oṣu January 1927, eyiti nwọn si gbe oku rẹ lọ sin si itẹ-oku ni idi-omọ Patty Street.

3. Iwe Ijọba (Nigeria Gazette) ti ọjọ 6 oṣu January 1927 sọ wipe Ijọba nfẹ gba owo-ori (Poll Tax) ni ọjọ 1 oṣu April 1928:—

*1st. Insertion*

A BILL ENTITLED.

An ordinance to Regulate the Leving and collection of A general Tax in the Colony.

BE IT ENACTED by the Governor of Nigeria, with the advice and consent of the Legislative Council thereof, as follows:—

1. This ordinance may be cited as the General Tax (Colony) ordinance 1927, and shall apply to the Colony only, and shall come into force on the 1st April, 1928.

2. There shall be Levied and collected, in manner hereinafter mentioned a tax (hereinafter called the general Tax") of ten shillings *per annum* payable be every male person of the age of sixteen years and upwards resident in the Colony.

4. Ipade awọn musulumi Eko (1) Jamat musulumi (2) Jamat Alkoranic, (3) Jamat Ahmadia, (4) Jamat Ọlọkọ 'Mosque, lọdọ Aṣoju-ilu (Resident of the Colony) Major Birrell-Gray, nipa ọran ofin owo-ori, eyiti Aṣoju ka fun won gẹgẹbi ohun ti o wa ninu Gazette" ti 6 January 1927.

5. Awọn Egbẹ Young Ansar-ud-Deen ṣe ayọ ọdun mẹta (Third Aniversary) ni ọjọ 22 January 1927 ni Egerton Road labẹ Alaga Lọya Jibril Martins B.L., L.L.B., (Lond.)

6. Ẹgbẹ Democratic Party ṣe ipade Gbogbogbo ni (Glover Memorial Hall) lọjọ 22 January 1927 nipa rọan ofin owo-ori, labẹ Alaga Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones, ati awọn isangbe rẹ Ọlọla Lọya Eric. O. Moore, J. Bagan-Benjamin, Lọya J. C. Zizer, W. A. Shacklefford, Thomas. H. Jackson, Herbert Macaulay, A. Bank-Anthony Alufa E. T. Johnson, L. A. Cardoso, ati Lọya T. A. Doherty, awọn oloye Eletu Odibo, oloye Oluwa, oloye Olumẹgbọn, oloye Ọlọtọ (Akilolu Akodu) oloye Aṣọgbọn ati oloye Oṣodi.

**Awọn isọri-sọri niwọnyi:—**

**Imam Saka Dabiri, Lemọmu Musa Amodẹ, Lemọmu Musa, Lemọmu Mọmọdu Nolla, Lemọmu Mọmọdu Belo, Lemọmu Ọbalende, Lemọmu** Sumọnu, Lemọmu Belo keji, Alfa Salami Ebute-Mẹta, Alufa Mọmọdu Eko, Seidu Disu Giwa, Brimah Igbo, Asani Okunrinjẹjẹ, Abudu Ramọnu Agoro, Alufa Sanusi, Mọmọdu Lawani, Mutairu Cole, Musa Bashọrun Lemọmu Alli, Amọdu Tijani, Kasunmu Ẹiyẹkọle, Alufa Sanni, Oseni Mogaji, Mustafa Alapafuja, Sulu Kaffo, Mustafa Aromaṣọdu, Sanusi Laguda, Suberu Aromaṣọdu, Momọ Agoro, Yesufu Ijaoba, Sule Balogun, Jinadu Matti, Disu Otun, Suberu Dawodu, Brimah Olowu, Yesufu Shofuntere, Alhaji Okunu (Ratibi) J. F. Ajọsẹ, F. C. R. Leigh, John K. Dawodu, J. K. Oduwọle, F. A. Thomas, J. A. Fashanu, J. A. Mọtajo, E. T. Green, A. O Cole, E. B. Thompson, S. A. Durosinmi, M. Macaulay, J. T Ogunlaiye, J. A. Fakolujọ, J. A. Oshodi, D. D. Folayin, E. A. Bright, D. O. Dusunmu, Duro Thomas, A. O. Sogunro, Prince John Kọsọko, A. Deniga, Aina Ọnabolu, Peirera, Bailey, Salvador, Theo Edwin ati awọn Jakanjakan pẹlu.

7. Onidajọ Maxwell ṣe idajọ Lọya L. B. Agusto pe ki o san Twenty-five Guineas fun mimu ti Oyinbo P. Shannon mu u wipe o di on lọwọ lẹnu iṣẹ.

8. Yesufu Omidiji Akotun wọ Iga ọlọtọ lẹhin Akilolu Akodun lọjọ 17 February 1927.

9. Akilolu Akodu pe Yesufu Omidiji, Lemọmu Kasumu Olokodana, Akisanya Mọgaji ati Bakare Oṣẹru lẹjọ pe on fẹ gba 550 Pounds nipa ọran ilẹkun fifọ ni Iga Ọtọ lọjọ 17 February: 1927, Lọya J. C Zizer lo wa fun Akilolu Akodu, Lọya Kitoyi Ajasa ati Lọya A. Alakija lo wa fun awọn Yesufu Omidiji, ẹjọ yi bẹrẹ lọjọ 2 March 1927.

10. Ọkọ-elefi T. M. V. "Apapa" ti awọn Oyinbo Ọlọkọ Elder Dempster wọ ile yi lọjọ 3, March 1927.

11. Idajọ ẹjọ Akilolu Akodu ati Yesufu Omidiji lọjọ 24 March 1927.

12. Dokita H. Ade Doherty ọmọ Ọgbẹni J H. Doherty Dokita Manuwa ati Lọya Siffre ba ọkọ Jamani "S. S. Wadai" de lati ilu Oyinbo lọjọ 26 March 1927.

13. Akilolu Akodu ṣe Apili (Appeal Case) lori ẹjọ Iga Ọtọ nipa Yesufu Omidiji lọjọ 28 March 1927.

14. Igbimọ-Aṣofin (Legislative Council) lọjọ 4 April 1927; iwe-ẹbẹ Ẹgbẹ Democratic Party nipa ọran ofin owo-ori si lọ si Igbimọ lọjọ yi.

15. Awọn Musulumi Eko kirun "Eidil Fitri" lọjọ 4 April 1927.

16. Ọlọla Gomina Graeme Thomson ati Iyawo rẹ ba Ọkọ "Appam" lọ si ilu oyinbo lọjọ 8 April 1927.

17. Oyinbo Birrel-Gray (Resident of the Colony) ba ọkọ "Appam" lọ si ilu oyinbo lọjọ 8 April 1927.

18. Lọjọ 19 April 1927 ni onidao P. B. Petrides ni ki Akilolu Akodu wa si Kotu fun ẹjọ ti Yesufu Omidiji pe e wipe ki o kuro ni Iga.

19. Akilolu Akodu kuro ni Iga Ọtọ lọjọ 23 April 1927. Nipa idajọ ti Kotu fun u ati ogun Pọnun ogun ṣile fun owo irin-ẹsẹ.

20. Waya de lati ilu oyinbo pe Prifi-Kasulu gba wipe ki nwọn ṣe ẹjọ Prince Eṣugbayi Eleko ni ilu oyinbo eyiti awọn ẹgbẹ Democratic fi iwe Akiyesi si ode bayi pe :—

The Nigeria National Democratic Party. Ilu Committee Section, leave has been granted by His Majesty's Privy Council in London during the forenoon to-day for the appeal of Prince Eshugbayi Eleko Lagos, May 9, 1927.

21 Emir Kano ati ti Kasaure de si ilẹ yi ni ọjọ 23 May 1927.

22. Emir Kano ati ti Kasaure lọ si ọdan lọjọ 24 May 1927 ọjọ-ibi Ọba (Empire Day).

23. Emir Kano ati ti Kasaure kuro ni ilẹ yi lọjọ 28 May 1927.

24. Iwe-irohin ilu oyinbo "West Africa" ti ọjọ 14th May ti o de si ilẹ yi lọjọ 1 June 1927, fi ọran gbigba Apili ẹjọ Ọmọba Eṣugbayi Eleko han wipe awọn Onidajọ mẹta yi :—Viscount Haldane, Lord Shaw ati Lord Warrington lo joko si ori aga, awọn lọya meji yi F. B. Merriman ati Horace Douglas lo wa fun Prince Eleko, Lọya S. E. Pocock lo wa fun titako iwe-ẹbẹ na.

25. John Henry Stanley-Robbin ṣe Awowo (At Home) lọjọ 2 June 1927 ni Gbagan ile ẹjọ fun ifẹhẹnti (Pension) ninu iṣẹ Ọba, Ọlọla Lọya Kitoyi Ajasa lo ṣe Alaga Awowo yi pẹlu awọn Lọya J. T. Nelson Cole ati Lọya O. Alakija, eyiti Ọgbẹni Robbin gba oye I.S.O.

26. Lọjọ 7 June 1927 ni Ijọba mu Ọgbẹni J. K. Coker ati K. Ajiṣafẹ pe nwọn sọrọ Ọba Ademola Alake li aidara sinu iwe-irohin "Eko Igbehin ti E. M. Awobiyi ati iwe-irohin "Eko Ọsọsẹ" ti Thomas H. Jackson.

27. Lọjọ 8 June ni Lawani Agbe Smith jalaisi ni Oshogbo.

28. Lọjọ 10 June 1927, awọn Jamat Musulumi ati Jamat Alkoranic lo kirun "Eidil Azan."

29. Ẹgbẹ Dẹmọ ṣe ipade Gbogbogbo lọjọ 11 June 1927, labẹ alaga Ọlọla J. A. Caulcrick ati awọn isrngbe bi Ọlọla Lọya Eric O. Moore, Thomas H. Jackson, H. Macaulay, A. Bank Anthony, J. Bagan Benjamen ati awọn oloye bi Eletu Odibo, Oloye Oluwa, oloye Olumẹgbọn ati oloye Oshodi.

Ipade ẹgbẹ yi sọrọ nipa wahala ti awọn aṣolu ṣe ni Igbimọ Aṣofin ti ọjọ 4 April 1927, nipa ofin owo-ori, nipa didagbere fun Ọlọla Lọya Eric. M oore i on pẹlu ọmọ rẹ nlọ si ilu oyinbo ati nipa ọran ẹjtọ Ọmọba Eleko ti o mbẹ ni ilu oyinbo.

30. Awọn Jamat Ahmadia ati Jamat All Ọlọkọ's Mosque lọ kirun "Eidil Azah" lọjọ 11 June 1927.

31. Oyinbo Olori ọlọpa Canvendish wa si ile-ẹgbẹ (G. M. H.) nigbati awọn Ẹgbẹ Dẹmọ nṣe ajọ lọwọ, Alaga Ẹgbẹ Dokita Caulcrick si pe'ṣẹ fun ẹgbẹ lẹsẹkẹsẹ awọn ọmọ-ẹgbẹ si tuwo fun lẹmẹta pe :—Muso ! muso ! ! muso ! ! !

32. Ọkẹ ogidan Iya-ẹgbẹ Ararọmi ọja ṣe alaisi lọjọ 12 June 1927, nwọn si gbe oku rẹ lọ sin si Ikoyi, awọn ojoye bi Eletu Odibo ati Oloye Oluwa ati awọn Ọgbẹni Herbert Macaulay ọgbẹni Thomas. H. Jackson, Lọya J. C. Zizer ati Brimah Igbo lọ si ibi oku yi

33. Ọlọla Lọya Eric. O. Moore ba ọkọ "Aba" lọ si ilu Oyinbo Ijọ 17, June 1927.

34. Iku Ọgbẹni Emanuel Makanju Awobiyi Olotu iwe-irohin "Eko Igbẹhin" ṣẹlẹ lọjọ 20 June 1927, nwọn gbe oku rẹ sin lọjọ 21st June 1927.

35. Iwe-irohin ojojumọ "Daily News" tun bẹrẹsi jade lati ọjọ 1st July 1927.

36. Iku ọgbẹni Ogunlana Arẹwa ṣẹlẹ lọjọ 7 July 1927, ni ile rẹ ni Ọbanikoro Street Lagos.

37. Ẹjọ Ọba Alake ati Ọgbẹni Coker bẹrẹ ni iwaju Adajọ H. S. Berkley lọjọ 13 July 1927, Lọya A. Fọlarin ati Lọya O. Alakija lo wa fun Ademọla, Lọya Jibowu lo wa fun Coker.

38. Iku Labuntu Arẹwa ti Oko-Awo ṣẹlẹ lọjọ 15 July 1927, nwọn gbe oku rẹ lọ sin si Yaba Cementary.

39. Ọgbẹni Isaac, B. Thomas di olotu Iwe-irohin Eko Igbẹhin lọjọ 15 July 1927.

40. Iku Lọya A. E. M. Gibson ṣẹlẹ lọjọ 18 July 1927, ni ilu Calabar.

41. Dokita N. T. Olhṣọga M.B. C.H.B., ba ọkọ "Wadai" de lati ilu oyinbo de si Eko lọjọ 24 July 1927.

42. ọwọn Ẹgbẹ People's Union ṣe ipade ni ile-ẹgbẹ ti (Ilupesi Hall) Ẹnu-Ọwa nipasẹ ọran ofin owo-ori lọjọ 26 July 1927.

43. Alaji Alasan Dantala (Hausa) ba ọkọ Faranse ti o njẹ "Padusay" de lọjọ 28 July 1927.

43. Bishop Eko, Aluta F. Melville Jones D.D., lọ ṣi Ṣọṣi Onidunkun (Breadfruit Church) lọjọ 29 July 1927, fun titunṣe ti nwọn yanri rẹ.

Awọn Samari ti o wa nibẹ ni Ọgbẹni Henry Carr, T. A. J. Ogunbiyi, Alufa Ṣọṣi na, Alufa James Pearse, M. S. Cole, H. V. E. Johnson, C. A. Ṣowunmi, W. R. B. Kuyẹ, Ọlọla Kitoyi Ajasa, Alufa, J. O. Lucas, J. J. Lucas, E. O. Bright, A. E. Norman-Willams, H. Afric

Williams, Kuṣẹka Taylor, C. A. J. Williams, E. O. Aiyede, J. K. Dawodu ati E. O. Oni lo mbẹ nibẹ.

44. Ẹgbẹ Democratic Party ṣe Ipade Gbogbogbo lọjọ 30 July 1927 labẹ Alaga Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones, M.B. ch. B., ati Ọlọla Dokita J. A. Caulcrick, T. H. Jackson, J. Bagan Benjamin, J. C. Zizer, A. Bank Anthony, T. A. Doherty, H. Macaulay ati awọn Ojoye Chief Eletu Odibo Chief Oluwa, Chief Olumẹgbọn ati War-Chief Oṣodi.

Ninu ipade, nwọn sọrọ nipa ofin owo-Ajulọ (Income Tax) lori eviti nwọn ṣe ipinnu pe awọn yio waya si Ọlọla Gomina Graeme Thomson, Ọlọla Eric O. Moore ati si Sẹkitẹri Ọba (Secretary of State for the Colonies) pẹlu ni ilu oyinbo lati reti iwe-ẹbẹ-ẹgbẹ nipa ofin yi.

45. Isabella Pratt ṣe alaisi lọjọ 13 August 1927.

46. Ọgbẹni Henry Carr I.S.O di ẹni ọdun mẹrinie-lọgọta lọjọ 16 August 1927.

47. Ajọ Igbimọ Aṣofin (Legislative Council) lọjọ 23 August 1927, labẹ Ọlọla F. M. Baddeley C.M.G., iye awọn ti o mbẹ ni Igbimọ ni iwọnyi:— H. M. M. Moore, Acting Chief Secretary to the Govt, Col. F. Jenkins C.M.G, Acting Lieutenant Governor, Southern Provinces, C. W. Alexander, Acting Lieutenant Governor Northern Provinces, J. C. Howard, Acting Attorney General, Dr. T. B. Adam, Acting Director of Medical and Sanitary Office, A. H. Hodes, Acting Treasurer, Captain R. H. W. Hughes C.B., C.S.I., C.M.G., D.S.O., R.D., R.N.R., Director of Marine, F. A. Clinch, Comptroller of Customs, G. J. F. Tomlinson Acting Sect. for Native Affairs, K. L. Hall, Acting Deputy Chief Sect. W. E. Hunt, Act. Sect Southern Provinces, E. M. Bland, C.M.G, General Manager of the Railway, C. L. Cox, Director of Public Works, G. I. Righton, Postmaster General, G. H. Findlay, Resident of the Colony (Extra Ordinary Member) C. C. Adeniyi-Jones Second Lagos Member, Kitoyi Ajasa, O.B.E, Member for the Colony Division, K. Ata-Amonu, Member for Calarbar, I. O. Mba, Member for the Ibo Division, S. C. Obianwu Member representing the Niger African Traders, S. H. Pearse, Member for the Ẹgba Division, E. H. Oke, Member for the Ọyọ Division, J. W. Speer, Commercial Member for Kano, Dr. J. A. Caulcrick, Third Lagos Member, J. Whitfield (Provisional) Member for Shipping, L. M. Herapath (Provisional) Banking Member, ati H. R. Routledge (Provisional) The Commercial Member for Lagos.

Ofin ti nwọn tun pinnu nipa owo-ori ni Igbimọ Aṣofin ti ọjọ 23 August 1927 na ni eyi:—

## SCHEDULE A.

### PART I.

Tax shall be paid by person resident within the Municipal area of Lagos at the rates set out in the following Scale, viz:—

Amount of chargeable Income per Annum Tax Payable.

| Not less than | but less than | £ | s. | d. |
|---|---|---|---|---|
| £30 | £50 | | | |
| ,, ,, ,, 50 | ,, ,, ,, 100 | 0 | 6 | 0 |
| ,, ,, ,, 100 | ,, ,, ,, 200 | 1 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 200 | ,, ,, ,, 300 | 2 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 300 | ,, ,, ,, 400 | 3 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 400 | ,, ,, ,, 500 | 4 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 500 | ,, ,, ,, 600 | 5 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 600 | ,, ,, ,, 700 | 6 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 700 | ,, ,, ,, 800 | 7 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 800 | ,, ,, ,, 900 | 8 | 0 | 3 |
| ,, ,, ,, 900 | ,, ,, ,, 1,000 | 9 | 0 | 0 |
| ,, ,, ,, 1,000 | ,, ,, ,, 1,000 | 10 | 0 | 0 |

and so on a tax of £1 being payable for every additional £100 of chargeable Income or part thereof.

### PART II.

Tax shall be paid by persons resident outside the Municipal area of Lagos at such rate as the Administrator, subject to the approval of the Governor, who may after or amend such rate as may appear just or expedient, shall decide.

Iye awọn ti o fẹ ofin owo-ori na ni iwọnyi:— The Hon. Member for the Ọyọ, The Hon. Member for the Colony Division, The Hon. the Acting Resident for the Colony, The Hon. the Postmaster-General, The Hon. The Director of Public Works, The Hon. The General Manager of the Railway, The Hon. The Act Sect Southern Provinces, The Hon. The Act Deputy Chief Sect. to The Govt, The Hon. The Sect for Native Affairs, The Hon, The Comptroller of Customs, The Hon. The Director of Marine, The Hon. The Act. Treasurer, The Hon. the Act Director of Medical and Sanitary Service. The Hon. the Act Attorney General, His Honour the Act Lieut-Governor, Northern Provinces, His Honour the Act Lieut-Governor, Southern Provinces and the Hon. the Acting Chief Secretary to the Government.

Iye awọn ti nwọn ko fẹ ni iwọnyi:—The Hon. the Commercial Member for Lagos, The Hon. the Banking Member, The Hon the Member for Shipping, The Hon. the Third Lagos Member, The Hon. the Commercial Member for Kano, The Hon. the Member for the Ẹgba Division, The Hon. the Member representing the Niger African Traders, The Hon. the Member for the Ibo Division, The Hon. the Member

Calabar, The Hon. the Second Lagos Member. For 17. Against 10.

47. Yesufu Ọba Adewọlẹ jẹ alaisi lọjọ 20 August 1927, ni ile rẹ ti Oko-awo.

48. Iku Disu Apata ṣẹlẹ lọjọ 24 August 1927, awọn sin oku rẹ si itẹ Abari.

49. Ọgbẹni Gregorio ti Glover Street, Lagos, ṣe alaisi lọjọ 2 September 1927.

50. Iwasu ikẹhin fun Dokita James E. Kwegyir-Aggrey, M.A., P.H.D., D.D., Etc., Etc., ni Ṣọṣi Ita Tinubu (Wesleyan Trinity Church) lọjọ 4 Sept, 1927 ẹniti o ṣe alaisi ni ilu New York, lọjọ 30 July 1927.

Orukọ awọn ẹniti o mbẹ nibi isin adura ọjọ na ni eyi:—Captain Lotinga (Aide-de-Camp) Ọlọla H. M. H. Moore, Bishop F. Melville Jones, Alufa T. A. J. Ogunbiyi, Ọgbẹni Henry Carr, A. Hobson, Ẹni-ọwọ H. V. E. Johnson, W. O. Aiyedun, S. V. Latunde, Herbert Macaulay, L. Duval, W. M. Peacock, J. Griffin, Ẹni-ọwọ A. N. Cole. Evan E. Williams, L. Potts Johnson, D. A. Takoe, T. J. Henry, J. A. Angus, Dokita Orişadipẹ Ọbasa (of Ikija) J. H. Stanley Robbin, Dokita C. C. Adeniyi Jones, P. J. C. Thomas, ati awọn jakanjakan.

51. Ẹjọ Alake Ademọla ati ọgbẹni J. K. Coker pẹlu K. Ajişafẹ bẹrẹ ni Kotu Ganran ti Abẹokuta ni oke Igbẹhin ni iwaju Onidajọ M. L. Tew, lọjọ 5 Sept, 1927. Lọya J. C. Zizer ati Loya Ayọdele Williams lo wa fun Coker, Loya O. Moore lo wa fun Ajişafẹ, Lọya O. Alakija lo wa fun Alake to pe ẹjọ.

52. Iku omidan Marth. K. Ṣowunmi, aya Ẹni-ọwọ Ṣowunmi ṣẹlẹ lọjọ 9 Sept, 1927. Bishop Jones, Alufa Ogunbiyi, ati H. E. V. Johnson lo ṣe adura si oku rẹ lara ni Ṣọṣi Onidunkun.

53. Reluwe Olokuta ati Mọto pade ni arin Ibusọ Iṣẹwọ ati Owowo lọjọ 11 Sept, 1927.

54. Oyinbo Ọgagun Birrel-Gray de si ilẹ yi lati ilu Ọba lọjọ 15 Sept, 1927.

55. Mọto Ibikunle Akitoye jona ni Onibudo Lane, lọjọ 18 Sept 1927.

56. Ẹjọ Ọba Alake ati J. K. Coker pẹlu K. Ajişafẹ bẹrẹ ni Kotu Igbehin Ganran Abẹokuta lọjọ 21 Sept, 1927. Ni iwaju Adajọ M. L. Tew.

57. Iku Iya-afin Rose Thomas, ṣẹlẹ ni ile rẹ Oluwole Street Lagos, lọjọ 24 Sept, 1927. Nwọn gbe oku rẹ lọ si Ṣọṣi Afrika (United Methodist) fun isin-ikẹhin lati ibẹ lọ si ile isinmi.

58. Ipade Ọlọla F. M. Baddeley ati awọn ara Warri lọjọ 30 Sept, 1927, eyiti o mu rukerudo ibọn yinyin dani lori ọran owo-ori.

59. Onidajọ M. L. Tew, ṣe idajọ Ẹjọ Alake ati J. K. Coker, ati K. Ajişafẹ lọjọ 4 Oct, 1927, pe ki Ajişafẹ san £25, Coker £100 tabi ẹwọn oṣu mẹrin, ati £75 owo irin ẹsẹ.

60. Iku John Frederick Coker (alias owo-iya) ṣẹlẹ lọjọ 18 Oct, 1927.

61. Iku Adebayọ Pratt ṣẹlẹ lọjọ 19 Oct, 1927.

62. Ọlọla Gomina Graeme Thomson K.C.B., ati Iyawo rẹ ba ọkọ "Abinsi" de si ilẹ yi lọjọ 20 Oct, 1927.

63. Oyinbo G. H. Findlay ati Oloye Ọbanikoro (Adẹmọ Akẹju) lọ si Agege lọjọ 24 Oct, 1927, lori ọran owo-ori.

64. Ẹjọ Lọya Zizer lọjọ 2 Nov, 1927, ni iwaju Onidajọ Ralph Combe ati M. L. Tew, eyiti oyinbo (Agbẹjọro-ọba) J. C. Howard pe e wipe o bura mọdaru kan lori ẹjọ John Adenigbagbe.

65. Aya Ọlọla Dokita C. C. Adeniyi-Jones ṣe Awowo (At Home) ni ile Afari Ogun (G. M. H.) lọjọ 4 Nov, 1927. Awọn ọgbẹni Herbert Macaulay ati awọn Saraki miran lo ṣe ẹyẹ nibẹ.

66. Iku iya-afin Jane Ibidun aya ologbe Burrel Vaughan ti Agarawu ṣẹlẹ lọjọ 5 Nov, 1927.

67. Iku oyinbo Lieut Col. F. Jenkins C.M.G, ṣẹlẹ lọjọ 8 Nov, 1927. Nwọn gbe oku rẹ lọ si Ṣọṣi (Colonial) ni ọdan fun isin-ikẹhin lati ibẹ lọ si Ikoyi.

68. Sẹkitẹri Ọba (Sect of State) kede ọjọ ikẹdun (Armistise Day) fun awọn ẹniti o gbọgbẹ loju ogun Ajakaiye 11 Nov, 1927.

69. Iwe-irohin ojojumọ (Nigerian Daily Telegraph) lati ọwọ A. Antus Williams lọjọ 12 Nov, 1927.

70. Awọn Onidajọ Ralph Combe C. J. Adajọ M. L. Tew ati Adajọ P. B. Petrides da Loya J. C. Zizer duro fun oṣu mẹta lọjọ 12 Nov, 1927.

71. Ọlọla Gomina Graeme Thomson, K.C.B, si ifihan Kalaba (Calabar Exhibition) lọjọ 21 Nov, 1927.

72. Iku ọgbẹni Alfred Silvanus Cole ṣẹlẹ ni ile rẹ Palm Church Street Lagos, lọjọ 5 Dec, 1927. Nwọn gbe oku rẹ lọ si ṣọṣi Onidunkun (Breadfruit) eyiti awọn Alufa T. A. J. Ogunbiyi, L.Th., Ẹni-ọwọ James Pearse, L.Th., ati Ẹni-ọwọ C. A. Ṣowunmi M.A., lọ ṣe iwasu ikẹhin rẹ.

73. Iku Dadi Irọko ṣẹlẹ ni ile rẹ Beckley Street Lagos, lọjọ 9 Dec 1927, nwọn gbe oku rẹ lọ si Ṣọṣi Aguda (Holy Cross Cathedral) lati ibẹ lọ si Ikoyi.

74. Ẹgbẹ The Nigerian National Democratic Party ṣe ipade gbogbo-gbo lọjọ 10 Dec. 1927, labẹ alaga Ọlọla Dokita J. A. Caulcrick ati Ọlọla Loya Eric O. Moore, Thomas H. Johnson, A. W. Shackleford, H. Macaulay ati Bank Anthony, ati awọn Oloye Eletu Odibo, Oloye Oluwa, Abagbọn Aşọgbọn ati Saka Oshodi. Nwọn ki Ọlọla Loya Moore ku abọ ilu oyinbo ti o de lọjọ (21 Oct.

1927) ati ṣawura bayi nipa Owo-Ajulọ (Income Tax) pe awọn yio ran ikọ lẹ fi irẹlẹ ba Ọlọla Gomina Thomson ṣọrọ, bi ko ba gba, awọn yio ṣe iwe-ẹbẹ si ọga awọn Gomina (Secretary of State) tabi ki awọn lọ si ilu oyinbo ninu oṣu March 1928.

75. Lọya Isaac Kuṣika-Robbert ti ilu Gambia wọ ẹgbẹ Democratic Party lọjọ 10 Dec. 1927.

76. Lọya Ewumi Macarthy de lati ilu oyinbo lọjọ 15 Dec. 1927, fun yiyanri iṣẹ amofin,

77. Ẹjọ Ajọṣẹ Onitana bẹrẹ lọjọ 15 Dec. 1927. Niwaju Onidajọ M. L. Tew, eyiti o pe awọn ara Idunmọta pe on ni ki Ijọba san owo ilẹ Idunmọta fun. Ajọṣẹ gba Lọya A. Desalu, ati Lọya E. J. L. Harrinson, awọn ara Idnnmọta gba Lọya E. J. Alex. Taylor, M. Akinṣemọyin, O. Alakija, J. H. Doherty, Latunde Johnson, A. Kayọde, Lọya Robbert ati Augusto.

78. Ogbẹni Herbert Macaulay ṣe wosika "Bareaucratic Autocracy Running Riot" Taxation Propaganda in the Warri Province (Protectorate) sinu iwe-irohin ojojumọ "Daily News" lọjọ 22 Dec. 1927.

79. Christmas Day 25th Dec, 1927.

80. Lọya S. Ayọdele Thomas, ba ọkọ Jamani "S.S. Wahebe" de lati ilu oyinbo lọjọ 31 Dec. 1927, lun pi pegede kikọ iṣẹ Agbẹjọro.

81. Iye ọmọbibi ni ọdun 1927 jẹ 2,739
Iye ofọ ti o ṣẹlẹ fun ọdun 1927 jẹ 1,839

Kurukuru bete, Amọdun, bayi l'ẹ o ba wa Amọdun ! ! !

Emi ni tiyin nitotọ,
KEKERE AWO.

---

# EKO AKETE

ẸKO, SATURDAY, JANUARY 7, 1928.

## ỌSAN TO GB'ALUMỌ LỌ SOKE, FUN LE GB'ALUMỌ SỌKALẸ.

Ọrọ ọrin yi ni o wa si ẹnu wa nigbati a gbọ pe boya Ijọba tun npete lati da ọrọ ti owo asingba lori dukia ẹni ti nwọn ni yio bẹrẹ si di gbigba lọdun ni, ro, a si gbọ pe boya nwọn tun le pada si eyiti nwọn ti wi ni pe yio jẹ ri owo ori: ẹn ti o ba ka *Nigerian Daily Times* ti *Monday* ọsẹ yi yio ri pe ọrọ na jọ gate ko jọ gate, o nfẹ fi ṣe mejeji tiro.

Loju wa a nbẹ Ijọba pe ko si awawi ti nwọn le ṣe pe ko si owo lọwọ wọn ti yio mu gbigba owo-ori yi di jaguda pali nitori ko si igba kan ti Ijọba lalaṣi owo lati ma fi ba iṣẹ wọn lọ. Ẹbẹ ni a bẹ ki nwọn ki o jare ki nwọn maṣai dẹkun gbigba owo yi, iba ṣe ti owo lori dukia ẹni ni tabi owo-ori nitori inira ti a fora pe yio ti idi rẹ jade gẹgẹbi gbogbo ilu ti nṣadura pe ki Oluwa maṣai pa'na inira nla yi, Baba na yio ṣanu fun gbogbo wa, yio si sọ imọran gbigba owo asingba yi d'oku larin wa lagbara Soko.

Oluwa ni yio gba Abudulai l'oko Olowo, Imale ki singba.

---

## INCOME TAX TABI ESU ADAIKO.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Mo bẹrẹ l'oji

Nigbati ẹni to npe ni ko dakẹ, o ṣoro ki a to le gbọ agbọya. Niwọn igbati Ijọba ko bai ti pa ofin buruku, ofin owo esu adaiko yi rẹ ninu iwe ofin *Nigeria*, o ṣoro ki a to le ye ọrọ sọ l'ori rẹ.

Ipade Igbimọ Aṣelu (*Legislative Council*) di oṣu to nbọ, lagbara Baba, ẹnu ki yio si ya ni lati gbọ pe awọn Ọlọla to wa nibẹ, ati Oyinbo Enia Dudu, a ko wipe awọn Oyinbo Oniṣẹ Ọba tabi awọn Enia Dudu to ti gbe kọnkọ pẹlu ọpọlọ mi, ti o ṣe wipe *I concur* nikan ṣa ni nwọn nwi si ofin kofin ti Ijọba ba fẹ lati sọ, yala ofin rere ni, tabi ofin buruku.

Ṣugbọn awọn Oyinbo Ọlọla atata ati Enia Dudu Ọlọla atata ani, ẹnu ki yio ya wa rara lati gbọ pe awọn pẹlu Ijọba tun fi pẹki ko pẹki l'ẹkan si i, nidi ọrọ owo buruku ti a ko jẹ ti Ọlọrun ko si ni jẹ ki a ri ni igbonsẹ yi.

Kilo ku nipasẹ ọrọ owo yi ti a ko ti sọ, kilo ku nipasẹ rẹ ti Ọlọla Dokita Jones ko ti la ni alaye yekeyeke, ani, kilo ku ti egun nla papa ti nfọhun bi enia ko ti sọ nipasẹ rẹ ni Iwe irohin ojojumọ ti a npe ni *Daily News* ni lọlọyi?

Eti ilu lo ha di tabi eti Ijọba? Eti ilu ko di rara, Ijọba lo ni lati yọ owu elepo to wa leti rẹ kuro ki o si gbọ igbe ati ẹbẹ wa ni agbọye. Egun to gbe agọ wọ tan, to tun mu ọpa dani, ko mọ iyi ara rẹ ni; bi ko tilẹ mu ọpa dani iyi ati ẹru to wa lara rẹ ti to ṣa fun.

Loni, Ijọba lo wa ni ipọ ẹgun bẹ to tun mu ọpa dani nitori ki a le mọ pe on ni ipa ati agbara ju wa lọ. Iwa Ijọba nigbamiran lori ọrọ bi iru eyi nmu ni ro pe irọ pupọ ko si ninu ọrọ ti awọn agbodegba nsọ wipe Ijọba nsọ larin ara wọn nigbati nwọn ba de Ikoyi. Irọ na ni pe :—Ijọba nbinu si Eko nitoripe oju Eko la ju ti ilu yoku lọ ni *Nigeria*, ati pe ti awọn ba sa ti daba lati so ofin kan Eko ṣa lo kọkọ ntakọ nwọn ; yala ofin na dara ni o, tabi ko dara, awọn ni lati fi jaguda so ofin na, nitori ki ara Eko le mọ pe awọn Ijọba ni agbara ju wa lọ.

A pe e ni irọ, nitori a ko rope Ijọbe jẹ huiwa bi majeṣi bẹ ; ṣugbọn nitori aibamọ, bi iru ero bẹ ba wa lọkan Ijọba nigba kigba kan ri, o yẹ ki nwọn jọwọ tori Ọlorun mu iru iro bẹ kuro lọkan wọn. Ero buruku ni.

A ko gọ de ibi ki a maṣe le mọ pe Ijọba lagbara ju wa lọ : ibaṣepe wọn ko lagbara ju wa lọ, Ọba King ilu Oyinbo ninu Ọla nla rẹ a fun Sẹkitẹri Agba ti Ijọba ni oye kun oye ni lọlọyi, ao ma wipe a yọ fun un. Gẹgẹ bi Enia Dudu, ọre kini Ọlọla F. M. Baddeley ti ṣe fun wa lati igbati o ti wọ ilẹ yi. Sibẹsibẹ, a ni ireti pe akọko kan nbọ wa nigbati Sẹkitẹri yi yio bẹrẹ si ṣe ohun wọuni ti yio dun mọ Ilu ninu.

Esa adaiko ti Ijọba fẹ gba lowọ wa yi, ọna ko jẹ bẹ. O pe enia ni ọmọ ọrẹ rẹ o kan an ni iko lori, ori rẹ nṣẹjẹ, o ni o nba ṣire ni. Ibaṣepe o nbaja ni nkọ, tabi ki o jẹ ọmọ ọta rẹ, itu wo lo ku ti o ba tun pa fun un ?

Ọtọkitọki a wa labẹ abo asia Ijọba Gẹsi ni yi, ni nwọn tun fẹ fi iru ofin buruku bi eyi ni wa l'ara. Kini a tilẹ ṣe, kini a gbe ni igba wọn ki a to di ole ; họwu, kilo kuku ṣe, a ha le ba enia tan, ki o si tori bẹ fa ni ni itan ya ?

Ti o ba ṣe pe ọda owo da Ijọba, tayọtayọ ni ao fi ṣe iranlowo fun wọn l'ọna kọna ti nwọn ba fẹ to ba si dara ; ṣugbọn nigbati ko si iyẹn nbẹ, kini nwon fẹ gba iru owọ bayi lọwọ wa si. Owo na ko tọ suna rara.

Nitorina, a bẹ Ijọba, a tun tun bẹ, ki o jọwọ da ọro na ro fun wa, ti o ba si pa ofin na rẹ nipa sisọ di oku, iyẹn ko wipe ki a maṣe mo pe Ijọba ni agbara ju wa lọ, a t mọ eyini ti pẹ.

Bi Ijọba ti ni agbara ju wa lọ, bẹ gẹgẹ ni ẹranko igbẹ papa ni agbara ju ara wọn lọ ; inira ti alagbara ẹranko igbẹ ko si fun alailagbara ẹranko ẹgbẹ rẹ, o ha yẹ ki awa ẹda ma fun ara wa ni iru inira ti ẹrako ko jẹ fun ara wọn. Ati awa, ati Oyinbo, Ọlorun sa ni agbara ju gbogbo wa lọ nitorina, bi a ko tilẹ bẹru ara wa, o yẹ ki a ma bẹru Ọlorun ninu iwa ati iṣesi wa si ara wa nitori ẹsan Ọlọrun, ati igbati Ọlorun ba bẹrẹsi bẹ ẹsẹ baba wo lara omo lati irandiran ẹkẹta titi de ẹkẹrin ọmo Oyinbo.

Alukọngọ, a fi kọ nyin l'ọrun.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

### OLUSAKIN'S COLUMN.

#### Wedding Bells.

A marriage between Miss Augusta Ebun Davies, the daughter of the late Mr. M. W. Davies (alias Ṣekoni) and Mr. A. Shelford O'Connor Williams, the eldest son of Mr. V. O'Connor Williams, was solemnised at Wesleyan Trinity Church, Tinubu, Lagos, on Thursday the 29th day of December, 1927, at 10.30 a.m.

The Ministers who took part in the ceremony were Rev. A. N. Cole, Rev. E. E. Williams, M.A., Rev. L. R. Potts-Johnson and Rev. T. Henry. Mr. P. D. T. Shaw was the bestman.

The bride who was given away by her brother Mr. R. S. Davies, Schoolmaster, St. Paul's Breadfruit School and the bridesmaids and pages were in gorgeous robes.

Among those present at the Wedding may be mentioned Dr. O. Ṣapara, I.S.O., P. J. C. Thomas, Esq., Dr. K. & Mrs. Faderin, G. T. Bickersteth, Esq., Solomon Sogbesan, Esq., J. H. Glover Willoughby, Esq., Adeniji Olugbile, Esq., T. Ekundayọ Williams, Esq., B.L., Mr. & Mrs. Labode Williams, Ayodele Williams, Esq., B.L., Abiodun Abayomi, Esq., B.L., C. A. J. Williams, Esq., D. Ayodele Bright, Esq., Herbert St. James Williams, Esq., Mr. & Mrs. B. O. Taylor, Ojo Cole, Esq., M. W. Davies, Esq., S. J. Cadmus, Esq., R. A. Ajayi, Esq., Raimi Bada, Esq., Mrs. Kitoyi Ajasa, Mrs. V. O'Connor Williams, Madam Flora Cole, Mrs. N. T. O. Davies, Madam Felicia Johnson, Mrs. A. S. Coker, Mrs Sarian Williams, Mrs. Clara Macaulay, Mrs. Ọmotunde Lawrenzo, Mrs. Elfrida Thomas, Mrs. S. Jones, Mrs Adum Bailey, Mrs. Adelaide Sagoe, Mrs. Hannibal Johnson, Mrs. N. F. Williams, Mrs. St. Anna, Madam Gbadero Benda, Miss Roda Cole and Miss Ayodele Davies.

Rev. T. Heury read the exhortation from the Psalm to the newly married couple. After the religious side of the ceremonies was over, reception was held in the Pavilion erected for the observance of the occasion at the residence of the Bride's father, 28, Taiwo Street, where elaborate refreshments and drinkables were liberally served by Messrs. R. S. & M. W. Davies.

At the table of reception where some toasts were proposed and responddded to by Barrister T. Ekundayo Williams, Mr. R. S. Davies, A. Shelford O'Connor Williams, the Bridegroom and other gentlemen. Mr. D. Ayodele Bright had the honour of being appointed a Master of Ceremonies.

We wish the Bride and Bridegroom, a happy home, longevity and all connubial bliss.

#### The enrolment of Mr. S. Ayodele Thomas, Barrister-at-Law.

Our new fledged Barrister Mr. S. Ayodele Thomas, was duly enrolled Solicitor of the Supreme Court of Nigeria, before Mr. M. F. Hincks, Esq., Chief Registrar, on Tuesday, the 3rd day of January, 1928, at 9 in the forenoon.

Mr. Thomas was formally introduced to His Honour R. M. Combe, Chief Justice, by the Chief Registrar the following day just before the rising of the Court.

We had followed with interest Mr. Thomas's career in England as a student and apart from being called to the Bar, he also matriculated in the University of London and was successful in the inter L.L.B. London Examination.

We wish him good lack and plenty of guineas.

**New Year's Honours.**

His Majesty the King has been pleased to confer New Year's Honours on the following Africans who had served and are still serving in Nigerian Government :—

Sir Frederick J. D. Lugard, former Governor -General of Nigeria and British Member on the Permament Mandates Commission of the League of Nations, as BARON.

Sir Graeme Thomson, Governor of Nigeria, as Knight Grand Cross of Saint Michael and Saint George, (G.C.M.G.)
And Knighthood for the Hon. F. M. Baddeley, Chief Secretary to the Government.

Congratulations to all concerned.

**Slavery Abolition in Sierra Leone.**

Laws abolishing slavery in Sierra Leone Protectorate become effected to-day. Two hundred and fifteen thousand slaves are due to be set free.—*The Nigerian Daily Times*, 2/1/27

**On Leave.**

Mr. M. L. Adigun, 1st Class Clerk, Acconts Department, (Traffic Audit Section), Ebute Metta, is on 2 months' vacation leave, as from the 2nd January, 1928. Mr. Adigun proposes to spend part of his leave at Isẹhin.

OLUṢAKIN

## IWA—AGBARA TI ẸKỌ ILE NI.

*( Translated from "Character by Dr. Smiles" )*

APA KARUN.

Ni iṣe asọdun ti a ba sọ pato pe bi obinrin ba ti lo agbara ti a fũn ni ṣiṣe akoso ile rẹ si; bẹni aiye ma fi ni irọra tabi oṣi, ilaju tabi ailaju, imọ tabi aimọ to. Otitọ ni Emerson sọ nigbati o wipe, "ilaju tabi ọgbọn ti ko fete wa." Nigbati a ba nwo ikoko lẹsẹ iya rẹ, a le sọ pe awọn ẹni igba ti nbọ ni a nwo un. Ẹkọ ti olukọni rẹ kini, eyiti o ju gbogbo awọn olukọni miran ti o le ni lọ, ba kọ ọ, irufẹ apẹrẹ ti o ba fi siwaju rẹ ni yio sọ irufẹ enia ti ọmọ na yio jẹ lẹhin ọla.

Ninu gbogbo awọn olukọni, obinrin ni ifi ifẹ kọ ni. Ọkunrin jẹ ọgbọn ori, ṣugbọn obinrin jẹ ọkan ifẹ ẹda enia; ọkunrin ni i ro apade ati alude, obinrin ni imọ idunra tabi bi nkan ti ri lara; ọkunrin ni agbara tabi okun, obinrin ni ẹyẹ, ẹṣọ ati itunu.

Obinrin ti o tilẹ gbọn ju laiye yi, ọna ifẹ ni ọgbọn rẹ a mu. Nitorina ni o fi jẹ pe, ọkunrin le tọ ni lọna ti ọgbọn ori, obinrin ni ikọ ni ni ifẹ tabi bi a ti nmọ nkan lara, eyiti ifi iru iwa ti a o hu han. Bi ọkunrin ti jẹ ti oye ori bẹni obinrin jẹ ti ifẹ.

Obinrin a mu ni ni ifẹ ohun na eyiti ọkunrin ko le mu ni ṣe ju ki a gba lasan lọ! obinrin si ni ẹni pataki ti imu ni mọ iwa rere.

Igbesi aiye St. Augustine jẹ apẹrẹ nlanla ti a fi le mọ agbara ti baba ati iya ni, olukuluku lọna tirẹ, lori iwa ọmọ.

Bi baba Augustine, ẹniti o jẹ talaka ni Thagasta, ti o si mọ riri ẹkọ ti ọmọ on ni, ti ntiraka lati fũn ni ẹkọ ti o ga ju ni ile iwe, ti gbogbo awọn aladugbo rẹ nyin nitoriti o sẹ ara rẹ "pe bi o ti ni ẹkọ lọ" ki ọmọ rẹ ba le ni ẹkọ giga yi—bẹni iya rẹ Monica, mu ọna tirẹ, o nkọ ọmọ rẹ ni iwa rere, o nfi ọna iwa mimọ la ni oye, o fi nrọ ọ, o fi nkọ ọ ni iwa mimọ, ninu ibanujẹ ti ko l'ẹgbẹ, nitori iwa buburu ọmọ rẹ, ko dẹkun ma gbadura fun titi adura rẹ fi gba. Bayi ni a ri i pe ifẹ rẹ ṣẹgun nikẹhin, suru ati iwa rere iya si ri esi rẹ gba ki iṣe ni ti ọmọ rẹ nikan, ṣugbọn ti ẹkọ rẹ ti o yi pada pẹlu.

Nigbati o ṣe, lẹhin iku ọkọ rẹ, ti ọkan fa a, o lọ ba ọmọ rẹ ni Milan, lati lọ boju to o; nibẹ ni titan si ba a, nigbati ọmọ rẹ di ẹni ọdun mẹtalelọgbọ. Ṣugbọn lati igba ewe ni iwa ati ẹkọ iya rẹ ti mu u lọkan sinṣin, eyiti o wa di iwa en papa.

*Koi pari.*

***Translated By***

ADEYINKA AJAGBE-OSA.

## ỌGBẸNI MACAULAY, C.E.

Ogọrọ enia ni awọn ti nwọn sọ pe gbakan nṣubu ni wosika ti Ọgbẹni wa yi kọ si Gomina Agba ti a si tẹ sinu Iwe-irohin *Daily News* ti oṣu to kọja; inọle

nlanla si ni pupọ enia jẹwọ pe nwọn ri ninu wosika na papa nigbati nwọn kã ni ti Yoruba ninu *Eko Akete*, oni kọ ni Ọgbẹni wa yi ti nṣe 'we si awọn Gomina, talo le gbagbe wosika ti o ṣe si Gomina Egerton ni ọdun 1908, nipa ti ọrọ Railway. Mo si tanmọ pe ko si ẹniti ko ni ti ma ri imọlẹ ọrọ ilu ninu gbogbo wosika ti o tị nṣe, ti o si nhan ninu iwe-irohin ilẹ yi.

AJIṢEGIRI

---

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

## ẸGBẸ SERAFU.

Ni iwọn ọdun marun tabi ju bẹ lọ sẹhin, Alagba kan de si Eko lati wa kọ awọn Onigbagbọ bi a ti ngbadura.

Bẹni ẹsin adura ni ẹsin Onigbagbo ẹnikẹni ti o ba wa ninu ẹsin yi ni lati mọ adura gba, nitori a ka ninu Bibeli pe, ẹkọ kini ti Jesu kọko awọn ọmọ ẹhin rẹ ni lati gbadura, Adura na si bẹrẹ ni Orukọ Ọlọrun, nipa eyi a ri pe Jesu fi Ọlọrun ṣe baba, ati pe bi ọmọ ti le sunmọ baba rẹ bẹ lo fi kọ wa lati ma sunmọ Ọlọrun, ki a si ma ba sọrọ gẹgẹ bi baba ati ọmọ ti le ma ba ara wọn sọrọ.

Alagba yi ti apele Orukọ rẹ njẹ Baba Aladura, a bi ni ilu Ikarẹ, ni apa Ilọrin: a gbọ pe a bi i ni arọ ko si le fi ẹsẹ rẹ rin fun ọdun pupọ, ko lọ si ile ẹkọ ri gẹgẹ bi a ti gbọ, sibẹsibẹ o si mọ pupọ ninu iwe Mimọ ni a ka sori, o jẹ on iyanu fun wa, oñ lo wa si Eko ti o si da ẹgbẹ "Serafu" silẹ nigbati wọn sọ fun un ni ile Ilọrin pe Eko yio parun nitori ẹṣẹ awọn ti o ngbe inu rẹ, on ko si kọ lati fi ara rẹ rubọ, ko si ku pẹlu ara Eko.

### IṢẸ.

Iṣẹ ti a gbọ pe on nṣe nigbati o de si Eko ni lati ma wasu n'ita gbangba pẹlu awọn ara ilu rẹ diẹ ni ede ti ko ye pupọ awa ara Eko tobẹ, ko si ri enia to ma wọ ẹgbẹ ti o nfẹ da silẹ, bikoṣe awọn ara ilu rẹ, ṣugbọn nigbati akoko de ti Ọlọrun nfẹ da lọla, o gbe ọdọmọde obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Abiọdun dide, ati nipa Iran ti o ni on ri, Ọlọrun fi ṣe afa-ero sinu ẹgbẹ yi; lati igbana ni okiki Baba-Aladura ti ka gbogbo ilu Eko ati agbegbe rẹ pẹlu.

Iṣẹ kini ti Baba-Aladura yi ṣe ni lati ma kọ awọn ọdọ (ọmọkọnrin ati obinrin) diẹ lati iwọn agogo mẹfa irọlẹ titi di bi iwọn agogo mẹjọ tabi mẹsan alẹ lati ma gba-adura nkan pataki ni eyi, nitori o nkọ won lati yipada kuro lọna egbe si ọdọ Ọlọrun.

Iṣẹ keji ni lati mọ Orukọ Ọlọrun ni orişirişi ọna bi a ti nkọ wọn sinu iwe Bibeli, a si ma kọ wọn ni itumọ rẹ pẹlu, ati iṣẹ ti nwọn nlo orukọ na fun, eyi jẹ ohun ti o dara pupọ-pupọ.

Iṣẹ kẹta ti o nkọ won ni lati ma gba awẹ, ati oniruru ọrọ ninu *Psalm*, ati iwe adura, ati ẹkọ miran ninu Bibeli ti yio wulo fun wọn lati ma fi gba'wẹ ati lati ma fi gba'dura pẹln.

Iṣẹ kẹrin ti o nkọ wọn ni lati ma fi ifẹ ba ara wọn lo—ati lati ma ba ọmọ ẹnikeji wọn gbe ẹru ara wọn—bi idamu ba de ba ẹnikẹni, yala o jẹ ọmọ ẹgbẹ wọn tabi ọmọ ẹgbẹ miran lode, ki wọn ma ṣe ara wọn bi ẹniti ọran na ko kan ti ndundun Ekute, ṣugbọn ki wọn pe ẹru na ni ti nwọn, ki wọn si duro ti ẹnikeji wọn na pẹlu adura ati awẹ.

Bẹ bẹ lo si nkọ wọn ni orişirişi ọna lati ma fi ẹmi sin Ọlọrun pẹlu igbagbọ to ye koro.

AKIYESI.

Pupọ ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ Serafu lo ni itara si ẹgbẹ, ati si ẹsin wọn, pupọ ninu wọn lo si njafara; Bi alebu ti wa ninu ẹsin Şọşi bẹni alebu wa ninu ẹgbẹ Serafu, kini ha mu eyi wa bikoşe ẹşẹ aigbọran, eyi to le awọn obi wa kini kuro ninu Ọgba Edẹni on ni koi ti dẹhin lọdọ awa ọmọ won titi di oni, ati pe gẹgẹ bi egbọn ti nlẹ mọ eti Aja tabi ara Malu bẹni ẹşẹ aigbọran yi lẹ mọ wa lara timọ-timọ bi eti ti nmọ ori nigba gbogbo ni Baba-Aladura ma nsọ ni ita gbangban pe on ko fi Ẹgbẹ yi di ẹsin kankan lọwọ, şugbọn imọlẹ ti wọn ba ri ninu ẹgbẹ Seraiu yi, ki wọn tan ina na si Şọşi tabi ẹsin miran ti wọn nlọ nitori o da ẹgbẹ yi silẹ lati fi agbara fun ẹsin gbogbo, ki Onigbagbọ le mọ pe, on ni ohun ija lọwọ, eyi ti o ju ti Baba-Alawo ati ti Onişegun lọ, şugbọn bi Eşu ti wa ni itẹlẹ ohun gbogbo ti o dara lati bajẹ, bẹni a ri ninu ẹgbẹ yi pẹlu, nitori wọn ko gbọ ikilọ yi, pupọ ninu wọn lo kọ Şọşi silẹ pata-pata, a si gbọ pe ẹlomiran ninu wọn wipe Alufa npẹ ju lati yọ orukọ on kuro ni kilasi.

A le bere bi o de inu Baba-Aladura nitotọ pe ki wọn ma lọ si Şọşi, tabi o nwi lẹnu lasan ni, bi a ti nri si, ati bi gbogbo akoko ti wọn nlo ni ile rẹ, eyi ti o dabi ohun ti o nfi fẹ ọla loju gbogbo enia, ki wọn le mọ titobi rẹ, dabi ẹnipe o nfi şe ete lẹşọ ni, ki a ma gbadura lati agogo mejila oru Satide (Saturday) titi fi di owurọ ọjọ Isimi, jẹ eyi ti o nfi di akoko Şọşi arọ lọwọ ati kilasi arọ Sonde (Sunday) pẹlu. Ninu isin ti alẹ, eyi ti wọn ni lati pejọ ni ile rẹ ki o to to agogo mẹjọ alẹ tun jẹ idiwọ fun isin ti alẹ pẹlu, ati akoko miran ti wọn ni lati ma pejọ ni ile rẹ ati lati ma korin akọ-gbadun, gbogbo rẹ ko fun wọn ni aye lati tun mọ ọna Şọşi tiwọn mọ, bẹni Baba-Aladura ko di wọn lọwọ, ọna wo ni a ni lati gba ki a to le tan ina igbagbọ Serafu si Şọşi to wa l'Eko nigbati a ko fun mẹmba laye lati da ẹgbẹ adura iru ti Serafu si Şọşi Eko ki ẹmi Ọlọrun eyi ti a ti sọnu ri le tun pada wa si ori ijọ Ọlọrun lẹkan si.

A şe akiyesi ohun pupọ ninu Ẹgbẹ yi, şugbọn ni pataki, a le sọ pe işẹ Adura wọn tayọ ti Şọşi pupọ, ati pe ẹkọ ti Baba Aladura fi fun wọn, pupọ ninu wọn lo nlo o si rere. Awọn ẹlomiran, ati pupọ ninu wọn lo npurọ tan ara wọn jẹ, nipa riri-iran, bẹni wọn ko ri nkan-kan, wọn a si ma fẹ ki a pe wọn ni mẹmba pataki; a ni pupọ ninu wọn ti iwa wọn ko yipada si iwa wọn lailai, ti wọn si nfi iwa ẹgbin wọn sọ ẹgbẹ d ra-dara yi ni orukọ buruku. Pnpọ ni Onigbcse ti o wa ninu ẹgbẹ yi, pupọ ni opurọ, pupọ ni iwa wọn ti nwọn nhu to buru ju ti Keferi lọ, bẹni awọn ni ẹni pataki ninu Ẹgbẹ yi, ninu iwasu ẹlomiran wa ri igberaga ninu ọrọ nsọ wọn, ẹlomiran a ma şepe pẹlu, bẹni a ko fi Kristi kọ wa bẹ—ọkọ ti o fun wa ni pe ka ma gbadura—ka masi şẹ epe, şugbọn ẹkọ yi koi ti ye awọn ẹlomiran ninu ọmọ ẹgbẹ Sarafu dara-dara.

IDA MIKẸLI.

Ohun şere-şere kọ ni ida Mikẹli, gẹgẹ bi awọn ọmọ-ẹgbẹ Serafu ti nma nlo o, Ọlọrun nikan lo ni aşẹ lilo rẹ.

Onigbagbọ totọ ni lati kepe orukọ Jesu fun iwosan gbogbo arun rẹ on si ni onigbọwọ wa ni ọjọ ajinde.

A le ma jẹ orukọ mọ awọn Angẹli ati awọn enia mimọ miran, şugbọn a ni lati ma ya ara wa si mimọ gẹgẹ bi awọn Angẹli ti ti wọn wa niwaju itẹ; ti jẹ mimọ.

Jesu ni ẹgbọn wa, on ni aşiwaju wa o si wa ni ọwọ ọtun Ọlọrun lati gbọ ẹbẹ ati aroye wa, ati ẹnikẹni ti o ba ti ọdọ rẹ tọ Ọlọrun lọ, ohun-kohun ti a ba nfẹ yio ri gba dajudaju şugbọn pẹlu ọkan igbagbọ ni o.

LAKOTAN.

A dupẹ lọwọ Baba ala-dnra fun işẹ ribi-ribi ti on şe larin Eko loni, a si tun bẹ ko şọra nitori ki awọn ti o nko jẹ, ki nwọn ma ba mu kọsẹ ki o ranti Mose, ti o nko awọn ọmọ Israli jẹ fun Ogoji Ọdun ni aginju, o kọsẹ ko si le de ilẹ Kanain, bẹni ẹşẹ igberaga lo mu eyi ri bẹ.

Ki ọmọ ẹgbẹ Serafu pẹlu ko şọra, nitori Eşu nba wọn jija-kadi pupọ, o si fẹ lati fa pupọ ninu wọn sinu agbo tirẹ; nitorina, ẹ di Amure nyin ki ẹ si mura lati ja-aja de opin, Ọlọrun yio si ja fun yin pẹlu, Amin.

JALANKATO.

---

"PARUNPỌ"

ni orukọ Iwe Egbogi titun kan ti agbajọ awọn Ẹgbẹ Onişegun kan ni Abẹokuta şe.

TABI TABI KO SI NINU RẸ PARUNPỌ GAN NI.

6/6d ni tita rẹ

(Owo lati fi ranşẹ si ilu okere 6d).

Ẹ o ri ra ni "Tika-Tore" Press, Broad Street, Lagos, ati lọdọ :—

JOHN ỌDUNTAN,
Ijeun, Abẹokuta.


Disinfectant Soap of Unrivalled Quality
Use Magnet Carbolic Soap in your home—it refreshes the skin and guards against infection. Made in three sizes, and obtainable everywhere.
MAGNET
Carbolic Soap Tablets
MAGNET
SOAP
WEST AFRICAN SOAP COMPANY LIMITED, APAPA.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nje pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.

**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC.

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer.

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes; these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

## Indents House.

Import of General Lines

Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

**A Trial is Solicited.**

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

## One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

# *ILE OWO OYINBO*

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmin ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to koj si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fur ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọtu 'ra wọn

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn

Pọ-ọ si ni owo wọn.

---

[Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer